# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI ŁẸJỌ'

VLO XIV NO 882 LAGOS SATURDAY AUGUST 17—AUGUST 23 KOBO MEJI (2D) 1963


### Sangba Fo! Olotu Ilu Congo F'ese Fe

# Awon Ogagun Fi Agbara Gba Ijoba Ilu Na

LEOPOLDVILLE—Sangba tun fọ ni ilu Congo ni ana nigbati Olotu Ijọba ilu Brazzaville (Congo) Balẹ Fulbert Youlon fi ẹsẹ fẹ ẹ, o ni on ju oye Olotu Ijọba silẹ on ko ṣe mọ, wara were awọn ṣọja jagunjagun ti gba gbogbo ile iṣẹ Ijọba na.

Ni ijẹrin ọjọ Iṣẹgun (Tuesday) ni ọpalaiye na bẹrẹ nigbati gbogbo awọn oṣiṣe ilu na faake kọri wipe awon ko ṣiṣẹ mọ nitoripe awọn ko fẹ ijọba alasokan ti ko ni alatako rara.

Nwọn ni iru eto ijoba bayi irẹjẹ ati inira ni Olotu na fẹ mu wa fun awọn ara ilu patapata. Nigbati awọn oṣ ṣẹ yi tọwọ lọ si ile Olotu na ọna ti nwọn bẹrẹsi kigbe pe awọn fẹ ki nwọn da awọn Olori awọn ti nwọn ti mọle bi beko awọn yio pa ijangbọn silẹ enia meji ni nwọn yinbọn pa patapata ni ọjọ ti awọn oṣiṣẹ na ja wole ọgba ẹwọn ti nwọn lọ da awọn aṣiwaju wọn silẹ nibiti nwọn gbe ti wọn mọ.

O to ọdun mẹta gbako nisisiyi ti Baalẹ ilu won na ti gun ori oye Alakoso ilu na; tẹlẹtẹlẹ iṣẹ Alufa Padi awọn Aguda ni o ti nṣe ri. Di igbati a nkọ irohin yi ọkan awa ilu ko ti balẹ nitoripe awọn oṣ ṣẹ ko ti pada sẹnu iṣẹ wọn.

# Adamu Pade Agbako Ni Fernandopo

ISABELLA—Awọn Cyabo Payan ti o wa ni erekusu ti nwọn npe ni Fernandopo Po ti o sunmo ilu Nigeria ni awọn ko fẹ awọn Hausa meji kan ti oruko wọn njẹ Malam Gamba Adamu ati Malam Sheriff Fani ni ilu [illegible] mọ, nitorina ki nwọn wa wọn kuro nilu ni [illegible]sa.

[illegible] ti awọn Hausa mejeji na ṣe ki o to di wipe nwọn wa wọn kuro nilu na ko ye wa rara ṣugbọn nkan ti a gbọ lẹnu awọn alara ni ọjọ marun ni awọn fi wa ni itimọle lai fi omi kan ẹnu rara.

A gbọ wipe awọn Hausa mejeji ti gunlẹ tọmọ tọmọ ati awọn iyawo wọn si Kalabar nisisiyi. Ọdun mẹdogun gbako ni nwọn ti gbe nilu na, nwọn kiṣe alejo rara.

Irohin ti a tun gbọ nipa awọn ọkunrin Hausa mejeji na ni wipe Ijọba ile wa ni Nigeria fẹ ba wọn lọwọ si ọrọ lile jade ti nwọn le wọn nilu na. Nwọn ni awọn fẹ mọ ẹṣẹ ti awọn mejeji ṣe ijọba Payan na.

## Afoju Kan Nko Won Niwe Nilu Hausa

KADUNA — Ko si ẹniti o wa laiye ti ko wulo ni iwọnba tirẹ, iyẹn ni ọrọ ọkunrin ti tiṣa afẹju kan ti orukọ rẹ njẹ Balarebe Hashim, ẹni ọdun mọkanlelọgbọn ti o nṣe iṣẹ akọwe ti o si tun nkọ awọn afọju ẹgbẹ rẹ ni iwe kika ati iṣiro owo.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ nipa afọju na, iṣẹ akọwe ni o ti nṣe nile iṣẹ ijọba ibilẹ Kano ki oju rẹ to fọ patapata ni ọdun kẹsan sẹhin. Ilewe ti nwọn npe ni Kofar Kudu ni Kano ni olọ ki o to bẹrẹ iṣẹ lẹhin eyi o tun lọ kọ iṣẹ akọwe ni ilewe giga Zaria.

## Awon Omo Egbe UPP Eko Yan Awon Oloye Won

EKO— Ninu ipade Kan ti awọn ọmọ ẹgbẹ selu tuntun ti nwọn ṣẹṣẹ da silẹ ti nwọn npe ni United People's Party ṣe ni Ebute Metta ninu ọsẹ yi ni a gbọ wipe nwọn ti yan Ọgbẹni C. Walton Waddel ti o nṣe Kontrakitọ ni alaga ẹgbẹ na.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na ti nwọn tun fun loye ni Ọgbẹni S.O. Kamson, igbakeji alaga; Ọgbẹni Ọlatunji Adewu, on paapa igbakeji alaga; Ọgbẹni Taju Thompson, akọwe ẹgbẹ na; Ọgbẹni Jaiyesinmi igbakeji akọwe; Oloye Fadun akapo ẹgbẹ; Ọgbẹni M. A. Momoh, akọwe ikede ẹgbẹ ati Ọgbẹni [illegible] akọwe eto inawo,


## LAGOS RACE CLUB

THE SECOND DAY August Race Meeting will take place on Saturday 17th August, 1963 First Race at 3·30 p.m.

Sweepstake will be drawn on the numbers of Admission Tickets, 1st will be paid £2. 10/-, 2nd £1. 10/-, and 3rd 10/-.

Two Silver Cups will be presented to the best [illegible] Ladies in national Costume and West[illegible] on the last day of this meeting.

COME ONE COME ALL

Hon. SECRETARY
LAGOS RACE CLUB.

## Omolaja Ja Ajaku L'Epetedo Ni Owuro Kutukutu

EKO—Agan bẹ ni Ẹpẹtẹdo L'EKO ni owurọ kutukutu ọjọ 'Ru ni ijẹrin nigbati awọn ọkunrin meji'kan lọ ara wọn mu papankoko ni opopo Dumaresque leti ibiti awọn munisifa ti nsun ilẹ ri, ti nwọn bẹrẹsi ja:

Ṣe enyin na mọ wipe ara EKO le wo iran? Gbogbo awọn ti nwọn ṣẹṣẹ ninu iyara wọn ni nwọ jade sode lati wo aw ọ ọkunrin mejeji bi nwọn mba ara wọn jagba.

Nwọn ko ri ẹnkan wipe "o t o nibẹ". Nwọn ja ija na titi ti ẹni fi bọ lẹnu ọkan ti awọn npe ni Ọlawunmi Ọmọlaja ti o ngbe agbole Jagun ni Ẹpẹtẹdo

Bi awọn ti nworan ti ri pe Ọmọlaja daku ni olukuluku ba sare wọ ile wọn lọ; awọn ọlọpa ni nwọn yara wa gbe oku ọkunrin na nibiti o gbe na gbalaja si ninu agbole Jagun na.

Iyawo ti o mba ọkunrin na gbe ti nwọn npe orukọ rẹ ni Ọmọmeji ti gbogbo ọrọ na ṣoju rẹ ti lọ si teṣan awọn ọlọpa lati lọ sọ tẹnu rẹ nipa nkan ti o fa sababi.

## Ara Pa Omo Alufa Ijo Sosi

GUSAU— Ọrọ ko dun lọjọ ti ara san pa ọmọ Alufa ijọ Ṣọṣi awọn C.M.S kan, ọmọ ọdun mẹrinla ti orukọ rẹ njẹ Kenneth Ezeani nibiti o gbe nṣere pẹlu ẹgbẹ rẹ kan.

A gbọ wipe lọjọ ti nkan na ṣe ni ojude gbangba kan nibiti nwọn gbe kọ ile ero (hotẹli) kan si ni ọmọ na pẹlu ekeji rẹ gbe nṣa yinyin ninu ojo ti o rọ arọrọda. Gbara ni ara na san lojiji ti o gbe ọmọ na lulẹ ati ekeji rẹ.

Ekeji rẹ ta gẹẹgẹ dide, o sa wọ'e lọ sugbọn ọmọ Alufa (Rev) L.O Ezeani ti to on pẹlu rẹ jọ nsere po ko le dide; nwọn sare gbe e lọ si ile iwosan ki o to de ibẹ o ti jalais patapata.


**Available!**

Choose your Mercedes-Benz 220s NOW.
A rich variety of colours is at last available.

MERCEDES-BENZ 220s



**LEVENTIS MOTORS LTD.**
LAGOS, (EB) IBADAN, KANO, KADUNA, JOS, PORT HARCOURT, ABA.

Sub-Distributors:

**ARMELS TRANSPORT LTD.**
BENIN CITY, ONITSHA, ABA.


## Awon Ole Oyinbo Da Oko Reluwe L'ona

LONDON—Awọn ọlọpa ọtẹlẹmuyẹ ilu Oyinbo ni ọwọ awọn fẹ tẹ awọn ọlọṣa danadana kan ti nwọn da ọkọ reluwe kan ti o nko ẹru owo iyebiye ati golu pelu dayamọnu (okuta olowo iyebiye) lọna ninu ọsẹ ti o kọja lọ yi. Ni ijẹta ni awọn ọlọpa gba awọn enia mẹrin kan mu leti ekun ninu awọn ọlọṣa ti nwọn lọ dana na pẹlu.

Irohin ti a gbọ nipa awọn ọlọṣa danadana ni wipe lọjọ Alamisi ti o kọja ni awọn ọlọṣa na yọ si dẹrẹba ti o nwa ọkọ reluwe na ni ojiji, nwọn ni ki o da ọkọ rẹ duro bi bẹkọ awọn yio fi ibọn paa. Lọgan ni dẹrẹba ọkọ na ti daa duro .

Awọn ọlọṣa na si ge ọkọ na si meji, nwọn fọ ilẹkun wọn nwọn si ko gbogbo apo ti nwọn di owo, golu ati dayamọnu si, nwọn bẹrẹsi da wọn sinu moto akẹru nla kan ti nwọn mu wa sibẹ. Gbogbo awọn ọlọṣa na ni nwọn fi aji-wọn soju.

Nwọn ni gbogbo nkan ẹru owo ti nwọn ko le ni ọkẹ marun lelọgọfa pọnun (£2,500,000). Ọwọ awọn ọlọpa ti tẹ abule ahere ti nwọn gbe ko awọn ẹru na si ni ilu Oyinbo, nwọn ko ti mu awọn enia mẹrin ati obirin kan ti nwọn mu lọ si Kotu.

A tun gbọ irohin wipe nwọn ti r owo ti o to Ọkẹ marun pọnun (£100,000) gba lọwọ wọn. Inu moto ayọkẹlẹ kan ti nwọn di wọn si ni awọn ọlọpa ri nwo na. Nwọn ko ti fọwọ kan wọn rara,

# Alaye Eto Ilera Ti Ijoba Fé Gbe Jade Fara Eko (4)

## Ati Iyawo

Ijọba Apapọ Orilẹ-ede Nigeria ni Eko nihin ti ya ọkẹ marundinlogoji ati ẹdẹgbajọ pọnun sọtọ fun ikikọ awọn ile-iwosan ti a o lo fun eta na. Gbogbo ẹru owo ti a o ba tun na lori eto ilera titud ati itọju awọn alaisan yi ni Ijọba Apapọ pẹlu gbogbo awọn ti nwọn da iṣẹ silẹ, ti nwọn si ngba awọn oṣiṣẹ sibi iṣẹ wọn, yio gce patapata.

Diẹ pere ninu owo sabua ti a o na lori eto, yi ni awọn oṣiṣẹ fun'ra wọn ma da lọṣọṣu ti nwọn yio si ma jẹ anfani itọju ọfẹ, yala gba ibuseu ni ile-iwosan ni tabi nwọn ti ile wọn lọ gba ogun fun itọju aisan ti o mba wọn ji.

Ṣugbọn ṣa, iye ti ẹnikọkan yio ma da loṣoṣu yatọ pupọ-pupọ nitoripe bi enia ba ṣe ngba owo oṣu to na ni yio da to loṣoṣu. Ẹniti o nṣiṣẹ ojnmọ ti o si ngba nkan bi ọkẹmeji sile lọsẹ eoi ni sile marun dinlogoji, yio ma da nkan bi ṣile kan sinu apo eto yi Nitoripe eto titun yi wa fun anfani gbogbo enia ilu Eko, awọn ,i nwọn lowo lọwọ dada, ti owo ọṣu wọn si ga, yio da iye ti o pọ sinu apo na lati ba le jẹki owo fun eto ilera ti tun na to lo.

## Ile Iwosan Ko To

Fun apẹrẹ, gbogbo wa ni a mọ wipe, gẹgẹbi ofin ilẹ wa, ko si oṣiṣẹ ti o le gba din ni ṣile marun ati kọbọ mẹwa lojumọ ni igboro Eko. Nitori bẹ, oṣiṣẹ ti o gba owo kere julọ l'Eko to si ngba ṣile marundinlogoji larin ọsẹ kan, ti o si san ni iyawo ati ọmọ yo tan ṣile kan lọsẹ fun ara re ati sisi fun awọn iyawo ati ọmọ rẹ sinu apo eto titun yi. Lẹhin eleyi, on pẹlu gbogbo awọn enia rẹ ni nwọn ni ẹtọ si gbogbo anfani eto ilera titun yi, lai tun ni san owo kankan mọ.

Igba gbokbo ni nwọn ma nsọ pe awọn oṣiṣẹ njẹ anfani itọju aisan wọn ni ọfẹ ni Eko nitoripe ofin ati adehun ile iṣẹ kọkan nibiti nwọn ti ngba awọn oṣiṣẹ na pese fun anfani yi. Ṣugbọn gbogbo wa ni a mọ wipe ko si ẹnikẹni to njẹ anfani itọju ọfẹ ti o pọ to nkan ni ilu Eko nitoripe awọn ile iwosan pẹlu ile itọju awọn alaisan ko tilẹ kaju iye awọn enia ti nwọn wa ni ilu na rara ni. Nipa ẹ. Ọpọlọpọ enia gẹgẹbi ati fihan tẹlẹ, ni nwọn san owo ribiribi fun awọn oniṣegun ni ikọrọ fun itọju ara wọn. Yio si jẹ aṣiṣọ ọrọ patapata fun ẹnikẹni lati ma polongo pe awọn kan wa ni Eko ti nwọn kii na owo fun itọju aisan wọn nitoripe awọn ti nwọn gba wọn si iṣẹ ti ni adehun kan

## Atomo

Ọpọlọpọ ninu awọn oṣiṣẹ ilu Eko ni nwọn ni iyawo ati ọmọ pupọ. Nitori idi eyi, ẹro Ijọba ni pe oṣiṣẹ kọkọn yio tun san ẹbu owo d ẹdiẹ lori awọn enia agbo-ile rẹ yi. Ebu owo lori awọn mẹbi yi ni nwọn ṣiro lori owo oṣu olukuluku, ki i ṣe lori bi ẹbi na ti pọ to. Eyi ni wipe ẹniti ẹbi rẹ kere ati eyiti tirẹ pọ, ni nwọn yio jijọ san iye kanna bi owo oṣu wọn ba ti pọ to. Aiamiran si ni wipe ẹbu owo ti olukuluku nilati san lori ẹbi rẹ yi yio jẹ idaji iye ti on pana ti san lori owo oṣu rẹ fun ara rẹ.

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

## Omo Re Jagun Molu:

# Iya Tiger Pa Ewure Bori

AMAIGBO (Ieba Nkwere)—Ayọ abara tintin! Iya Dick Iherigbo Ihetu, ẹniti gbogbo yin npe ni Dick Tiger, abẹṣẹ ku bi ojo ni on ko ri ohun fayọ, a fi ki o ma dapẹ lọwọ gbogbo ẹnyin ọmọ ile Nigeria ti ẹ duro ti ọmọ on ni Ibadan ni ọjọ Ẹti (Satide) ti o kọja nigbati o nja ija oye rẹ.

Gbogbo ẹnyin ọkawe Eleti-Ọfẹe ti gbọ bi Dick Tiger ti fi ẹṣẹ fọ Ọgbẹni Gene Fullmer, ẹlẹṣe kan pataki ninu awọn jẹṣẹ-jẹṣẹ ilu Amẹrika, loju ti o tun gbẹjẹ lẹnu rẹ. Ọgbẹni Fullmer paapa ko fi akoko sere, nitoripe ni owurọ ọjọ keji ni o ti ko ẹru rẹ ti o gba ilu rẹ lọ.

Irohin ti a gbọ lati ilu Amẹrika ni wipe inu iyawo Fullmer dun pupọ lati ri i,o ni inu on dun ti nwọn ke ba on fẹṣe fọ ọ loju. O ni ko si nkan ti o ma mbi on lẹru nigbakugba ti ọkọ on ba mba enia ja ju wipe ki nwọn maṣe ṣe jamba fun un lọ.

Baba Gene ti o ba wa si Nigeria ni on gbadun ilu ra.e ni awọn enia ibẹ feran alejo pupọ,bi nwọn ti nfi ọti ṣe alejo ni nwọn i fi nkan jijẹ tẹ enia lọrun. Baba Fullmer ni on ko ni gbagbe ilu ti nwọn npe ni Ibadan ni Nigeria.

O ju igba adiẹ lọ ti iya Tiger pa fi bọ ori rẹ ni ijẹta lọjọ ti ọmọ rẹ nṣe ajọyọ ogun ti o ja molu ati ọjọbi ti o tun ṣe.

Gbogbo awọn ara ilu Amaigbo ti o ngbe Apapa, Ajegunlẹ ni nwọn ṣe ajọyọ ija ẹṣẹ ti Tiger na ja. Gbogbo wọn da owo, nwọn ra ọti oriṣiriṣi, nwọn si tun fi nkan du Oloye ilu wọn Ọgbẹni J A Nwaosu ti o tile tọna wa si Ibadan wo bi Tiger yio ti ja raburabu si.

E Ka Iwe Irohin Eleti Ofe

HINDU SANKARA'S
Religious Art Jewelleries

Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas. Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.
Enclose 4/- British Postal Order by airmail for catalogues and literature.
HINDU SANKARA, 431 Archway Road, London, N.6, England

# ELETI–OFE

(A NJU WỌN KOSE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAM

28, Kosọkọ Street, Lagos, "ELETI-ỌFẸ" LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV. NO 882 SATURDAY AUG 17 - AUGUST 23 1963


## Sangba Fo Nilu Congo :

# Awon Osise Ni Awon Ko Fe Ijoba Alasokan

LEOPOLDVILLE (CONGO)—Sangba fọ ni olu ilu Congo ti nwọn npe ni Bazzaville ni ijarun nigbati gbogbo awọn ara ilu na ji lowurọ ọjọ na ti awọn obinrin ti o fẹ lọ ra nkan ni ṣọbu ko ri mọto bọsi wọ lọ, awọn ti nwọn fẹ fiwe ranṣẹ si idalẹ ko ri awọn akọwe posu ofisi da wọn lohun. Gbogbo awọn oṣiṣẹ ilu na ni nwọn ti binu da'ṣẹ silẹ patapata.

Kini o fa? Irohin fẹrẹ ti a gbọ nipa ọrọ na ni wipe Baba Fulbert Youlous tiṣe alakoso ijọba ilu na ṣe eto lati da ẹgbẹ oṣelu kan silẹ ti o jẹ wipe awọn ọmọ ẹgbẹ na nikanṣo ni nwọn yio ma ṣe ijọba, ko si ni si alakoso rara mọ.

Iru eto bayi bi gbogbo awọn oṣiṣẹ ilu na ninu, nwọn ni awọn ko fẹ IJỌBA ALAKOSOKAN ti ko ni ni orogun, ti ko ni ni ọbakan rara; nwọn ni ọna lati ma gba rẹ awọn ara ilu jẹ ni gbogbo rẹ. Nwọn fi ọrọ na logun, nwọn fi lọgbọn; Ọgbẹni Yonlon alakoso ilu wọn ni ni ki awọn olori gbogbo awọn oṣiṣẹ wa foju kan on ki on le ṣe alaye fun fun, awọn oṣiṣẹ na kọ ja'ẹ lati foju kan an nitoripe o ti da ẹgbẹ oṣelu ti yio ma lo fun ijọba alakosokan na silẹ.

## Awon Olori Sewon

Nwọn ni awọn gbọ wipe ninu oṣu yi ni awọn yio ma bẹrẹsi lo ofin tuntun ti nwọn ṣe fun Ijọba alasokan na nitorina gbogbo awọn oṣiṣẹ ilu na ba da iṣẹ silẹ pe ki o gbọ tawọn lori ọrọ ilu na ti o dabi ẹnipe o fẹ dikoko.

Ni ọjọ keji ti gbogbo wọn kọ ti nwọn ba fi-ọlọpa ko gbogbo awọn ti o jẹ pataki ninu awọn aṣiwaju awọn oṣiṣẹ na, nwọn si ti wọn mọ ọgba ẹwọn, ele mu ki inu bi awọn yoku wọn, nwọn si lọ ṣe ipade ma kan lori ọrọ.

Aṣẹhinwa aṣẹhinbọ nṣe ni gbogbo wọn ya wọ ọgba ẹwọn lọ, nwọn si da awọn aṣiwaju wọn na silẹ, ṣugbọn a gbọ wipe awọn enia marun ni awọn ṣọja yinbọ pa ninu wọn.

# Iwe Si Olotu

## Olorun B i Omo....

Inu mi yio dun ti ẹ ba le ba mi tẹ esi ọrọ yi si ọrọ ti Alufa Bawa kọ sinu iwe yin ti ọsẹ ti o kọja. Ti a ko le ọrọ ka bayi "Ọlọrun ko Bi Ọmọ" O si ya mi lẹnu pupọ lati gbọ wipe Ọlọrun ko bi ọmọ.

Mo fẹ ki Alafa na lọ wo inu iwe Bibeli ati iwe ti Alufa na gbagbọ ti wọn nye ni Alukurani ti wọn sọ wipe Ọlọrun sọkalẹ lati ọrun. Ki Alufa Bawa lọ wo Bibeli mimọ Mika 5: 2; Isiah 7: 14; Matiu 1: 18-22; Luku 1: 26-35; ati ninu Alukurani Saratu (Mọriamọ) 19: 16-22; Saratu 21: 26; Suratu 66 Aya 12 ati Suratu 21: 91.

Mo ro wipe bi Alufa yi ba lọ ka gbogbo awọn ẹsẹ ti ma yan fun lati iwe mimọ mejeji yi tan boya yio le da Alufa Bawa na loju ohun ti o wa ninu awọn iwe Ọlọrun tabi boya o le sọ wipe irọ ni iwe kan npa tabi iwe keji le parọ bi?

Ni gbogbo ọrọ ti Alafa Bawa sọ, ko yan ẹsẹ kan gbee lẹsẹ rara, a ko fẹ arofi sọ ọrọ rara. Ti ko bajẹ wipe Jesu Kristi jẹ ọmọ Ọlọrun, Ọlọrun paapa fun ra Rẹ ko ni funaṣẹ lati ṣe idajọ araiye, fun eri ẹ wo inu Bibeli, John 5: 25 29; Matiu 25: 31-34 ati ninu Alukurani Saratu 56: 1-9.

Ẹniti ki ba ṣe ọmọ Ọlọrun, Ọlọrun ko le le fun un ni aṣẹ lati ṣe iru iṣẹ pataki bayi. Ojiṣẹ Ọlọrun ni Muhamed ati Jesu ti a nsọrọ le lori yi.

Mo ro wipe Alufa yi nfẹ ki aiye ki o ma ẹsin ti o yẹ ki o tẹle ni o ṣe kọ iru iwe yi, gbogbo wa ni a le sọrọ, ṣugbọn awọn oloye ni ansọrọ fun, ko si yẹ ki a ma bu ara wa rara. Ki Oluwa ki o fun wa ni ẹmi gigun alafia ara.

Mo dupẹ lọwọ Olotu fun aye ti ẹ gba mi lati dahun ọrọ yi. Iwaju ni ẹbiti uyin yio ma re si.


Johnson St., Emi ni,
Eko. S A Ogunmọla


## Awon Ara Eko Ju Atata Nkan Nu

Mo gba fun ọrọ Olotu ti o jade ninu iwe Eleti-Ọfẹ ti ọsẹ ti o kọja ti nwọn sọ wipe awọn ara Eko ju nkan atata nu lori eto ilera tuntun ti Dokita Majekodunmi, minisita alamojuto eto ilera gbe jade ti awọn oṣelu kan ranri wipe awọn ko fẹ.

Nitotọ ẹsin ọta ẹni ki ga bi o ti wu ki o ga to, ko ga rara na ni a o wi. Ilu Eko ko bi ti atijọ mọ, bi ko ba jẹ be ni awọn agbalagba ilu Eko paapa ko ba ti pe ipade wipe ki gbogbo enia pejọ lati ba ọrọ eto ilera tuntun na fun wọn.

Nitotọ ni ọrọ ti ẹ sọ wipe ti o ba jẹ wipe Dokita Majekodunmi jẹ ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu kan ni nwọn ko ba lati fẹnu kan ọrọ eto ilera ti o gbe jade na, nwọn ko ba si ba a fẹnu pọn ọn daradara.

Bi ọmọ ẹgbẹ alatako ba mu imọran rere wa si ile igbimọ ko dara ni lọdọ ijọba wa, bẹ nwọn ko nṣe bẹ ni ilu Oyinbo.


Emi ni,
Martins Street, J. Afuapẹ
Mushin,


## Idanwo De Fun Awon Alufa Onikewu

IBADAN—Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun nwa awọn Alufa ti o mọ kewu ke kakiri igun mẹrin ipinlẹ na nitoripe nwọn tiṣe eto tan lati gba ogunlọgọ enia ti yio ma kọ awọn ọmọde ni kewu ninu ile iwe.

( Wo yoku loju ewe karun )

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

Lati Owo Ayiluka

## Awon Ara Ilu India Fe Ko Nehru Ni Olotu

NEW DELHI—Irohin kan ti a gbọ ninu ọsẹ yi ni ti awọn kan ninu awọn ara ilu India ti nwọn ni awọn bọ Ọgbẹni Nehru ni alakoso ilu awọn, nwọn ni ti ko pa nfẹ ijangbọn ko fi iṣẹ Olotu silẹ patapata eyiti o ṣe nibẹ to.

A gbọ wipe ni owurọ ijẹrin ni awọn bi ọkẹ marundinlogun enia lọkunrin ati lobinrin kawọ lori gba ile Ijọba ti Nehru na ngbe lọ, ti nwọn nlọgun too wipe ki ye bawọn ṣe eto ijọba mọ, gbogbo nkan onjẹ ni o wọn nilu, ko si si owo tobẹ nilu paapa ti awọn le tọwọ bọ na mọ.

Gbara ti awọn ẹgbẹ oṣelu ti Ọgbẹni Nehru paakati gbọ tito ti awọn alakoso yi to lọ ba baba ẹgbẹ awọn nile nṣe awọn na ko ara jọ, ti nwon gba ojule Nehru lọ ti nwọn nkigbe too wipe awọn mbẹ lẹhin alakoso na.

Ọrọ rogbodiyan na ko ti fori ti sibikan di igbati a nkọwe yi lọwọ.

## Idanwo De Fun Awon Alufa Oni-kewu

( O bẹrẹ loju ewe kẹrin )

A gbọ wipe nwọn ti fi iwe ikede sita nisisiyi wipe awọn ti nwọn ba mọ kewu na ke dopin ti nwọn si le ṣe waasi ma bọ wa fun idanwo lori imọ wọn na.

Orukọ ilu mẹfa ni nwọn darukọ wipe enia ti le ṣe idanwo mo-mọ-kewu-ke na, awọn ilu mẹfa na ni Akurẹ, Ibadan, Ijẹbu-Ode ati Ọyọ.

Nwọn ni gbogbo awọn Alufa ati ọmọkewu ti nwọn ba da ara wọn loju wipe awọn mọ ede Larubawa ti nwọn ba wa l'Eko le wa ṣe idanwo ti wọn ni Ikẹja tabi Agege, awọn Alufa ilu Ẹgba le lọ ṣe idanwo ti wọn ni Ibadan, gbogbo awọn onikewu Ijẹbu ti o mbẹ ni Shagamu ati Ikorodu ki nwọn gba Ijẹbu-Ode lọ.

Ni ọjọ keje oṣu ti mbọ ni nwọn yio ṣe idanwo na kakiri gbogbo awọn ilu ti a darukọ yi. Ibẹru ko si bi o ko ba gbọ oyinbo tobẹ, o le kọ iwe idanwo tirẹ ni ede yoruba.

# Ogun Arrives From U.S.A.



**Prince M.A. Ogun, president of Island Club, Lagos is here seen in this picture dancing with Mrs M.A. Tokunboh wife of the Secretary of the club at a Party. Prince Ogun arrived from United States on Thursday.**

# Eleti-Ofe D'araba

# Alaye Eto Ilera Ti Ijoba Fe Gbe Jade

## (o bere loju ewe Kefa)

lati fun wọn ni aufani itọju ọfẹ.

### Ofe Nibusun

Ni abẹ eto iṣẹ ilera ati itọju awọn alaisan ti a nlo lọwọlọwọ bayi, owo ibusun ninu awọn ile-iwosan wa bẹrẹ lati ori şile kan ati abọ de ori şile mẹwa ati sisi lojọ. Ni abẹ eto titun yi, nıwọn igbati enia ba ti san ebu owo tirẹ, ọfẹ ni ibusun ati itọju pẹlu egbogi ni gbogbo awọn ile-iwosan patapata.

Gẹgẹbi apẹrẹ miran, owo ibẹbi ti awọn aboyun nsan bayi bẹrẹ lati şile mẹwa ati abọ titi o fi de ori pọun merindinlogbọn ati şile marun fun igbẹbi ẹkan. Şugbọn ni abẹ eto titun si a o gbe jade yi, niwọn igbati ọkunrin kan ba ti san ẹbu owo ti o yẹ ki o san ọfẹ ni igbẹbi fun iyawo rẹ bẹni ọfẹ si ni itọju ti ohinrin rẹ yio gba şaju ati lẹhin ti o ba ti bi oyuu nu rei tan. Bakanna, ọfẹ ni itoju ti awọn ọmọ rẹ yio gba, lori egbogi, ehin tabi ogun ti nwọn yio ma le lati le fi le arun sẹhin.

### Eto Titun Na

Gẹgẹbi a ti şe alaye tẹlẹ olukuluku ti o ba ni ọmọ ati iyawo ni yio tun san ida ji ẹbu owo yi ki awọn ọmọ ati iyawo rẹ to le ri anfani itọju ọfe yi jẹ. IGBIMỌ FUN IṢẸ ILERA: Bi eto titun yi yio ba ni iyọri si rere, o şe pataki pupọ pe ki iṣẹ abojuto ati iṣakoso rẹ yatọ si ọna ti a fi nşe ise ilera ati itọju awọn alaisan ti a nlo lọwọlọwọ bayi.

Bi o ti wipe awọn enia ilu Eko ni eto titun yi kan gbọ-gbọn, nitorina iṣẹ abojuto ati iṣakoso eto na nilati fihan pe eto yi wa fun ra wọn şe abojuto rẹ.

Ero Ijọba Apapọ ni lati da Igbimọ kan silẹ fun iru arabaribi iṣẹ yi. Awọn yio jẹ ọmọ igbimọ yi ni awọn aşoju Ijọba apapọ, ti ẹgbẹ awọn to ngba oşişẹ, ti ẹgbẹ awọn oşişẹ fun ara wọn, ti Igbimọ Ijọba Ibilẹ Igbiro ilu Eko, ti ẹgbẹ awọn onişegun oyinbo, ti ẹgbẹ awọn olutọju alaisan, ati awọn aşoju awọn elomiran bẹbẹ ni olu-ilu orilẹ-ede Nigeria yi ni Eko.

A o tun da awọn Igbimọ kekeke silẹ ni awọn adugbo mọkanla ti nwọn pin Eko si fun eto ibo-didi. Awọn ara adugbo kọkan ni yio wa ninu Igbimọ adugbo wọn. Iṣẹ Igbimọ wọn si ni lati ma fun Igbimọ fun Iṣẹ Ilera, ti a ti kọkọ sọrọ rẹ, ni imọran lori abojuto iṣẹ-iwosan kekere ti adugbo ti igbimọ na ba wa fun. Igbimọ mejeji yi ni yio ri wipe awọn aşoju gbogbo awọn enia ti n ọn ngbe ni ilu Eko ni nwọn ninu lọwọ bi a ti nşe amojuto ati akoso eto ilera titun na, ti nwọn yio si tori be ka kun ti wọn. Eyi yio mu ki ifọwọsowọpọ wa larin awọn oşişẹ ti yio ma şişẹ labẹ eto titun na ati awọn enia arin ilu ti nwọn nşişẹ sin.




# Odo'gun Binu Ya Silu Ni Abeokuta

ABẸOKUTA — O to ọdun mọkanlelogoji ti Orişa Iyemaja ni ODO OGUN ti binu iru eyiti o bi lọdun ni. Ni ọdun na lọhun Odo Ogun ya wọ ilu Abẹokuta, o si ba ọpọlọpọ nkan jẹ ninu ọja kan ti awọn Ẹgba nna ni eti Odo na ti awọn npe ni ARARỌMI.

Eleyi ti o mu ki nwọn ko ọja na kuro nibẹ dọjọ oni; awọn ara Agọ-Owu ati Agọ-Ika ni nwọn ma nna ọja Ararọmi yi lojojumọ nigba na lọhun.

Ni ọsẹ ti o kọja yi ni gbogbo awọn Ẹgba tun niran jamba ti odo na şe nijọsi nigbati omi yi wọ ile ... ni Lafẹnwa ati Agọ-Ika. Gbogbo ile onile ni odo na ya ti o si ba wọn lẹnu jẹ jamburata.

Omi Odo na na kun tebẹgẹ ti o fi san ori gada Lafẹnwa.

Ni tesan ti nwọn npe ni Sanusi ati Arikọla leti Abẹokuta gbogbo oko ewedu ati awọn agbẹ da seti Odo Ogun na ni omi ti gbe lọ patapata, I an omi na le tobẹgẹ ti awọn atukọ paapa mbẹru lati gbe ọkọ wọn soju rẹ. Gbogbo ọkọ reluwe ti o nşi lati Eko ko le sare kọja ju Lafẹnwa lọ nitoripe omi ti kun bo oju irin ni tesan Arikọla lati lọ si Ibadan.

A gbọ lẹnu awọn agbalagba ilu Ẹgba wipe etutu ti nwọn ma nşe fun odo na ti nwọn npe ni ORIŞA IYEMAJA ti nwọn ko tun şe mọ lati bi ogun ọdun sẹhin ni o fa ki omi odo na binu ya wọle, şugbọn a ko ti gbọ wipe o gbe enia lọ rara.

Gbogbo awọn enia ti nwọn ni şọbu ati iletaja ni eti Odo Ogun na ni Lafẹnwa ni o ko ọja wọn lọ, o si sọ awọn elomiran di onihoho, o gba'le lori wọn.

A gbọ wipe odo na şe awọn ti o ngbe eti rẹ lọṣẹ ni ọna Ikorodu, gbogbo ile wọn ni o gbe lọ nibẹ.

BE TALLER

Increase your Height. Details free. Add:— C.T. Hospital, Azad Market,

Delhi 6, India.

# Paralyses

LONDON--Baba Yara, Ghana's international soccer star, who has been receiving treatment in a British hospital following a severe coach crash will be home today.

That is the good news given to a correspondent by a spokesman for the hospital, the Natinal Spine Injury Centre, Stoke Mandeville, Aylesbury. "Mr. Yara will be able to live at home and we have trained his wife to look after him. We have also written to the Ghana Health Serves explaining what further treatment he may need," he said.

Mr. Yara who suffered a fracture of the spine in a coach crash last March, was flown to Britain for treatment at Stoke Mandeville, where his wife, Patience, was in daily attendance on him at the hospital.

"His general health and condition is very good and there has been a steady improvement all the time," the spokesman added. When he first arrived in Britain he lay for several weeks totally paralysed, then gradually began to improve under treatment.

Recently he has been spending most of the day out of bed, siting in an arm chair. He has been rained to use special gadgets attached to his hands with which he has learned to type, feed himself and to do other personal things such as brurshing his hair But it is thought "very doubtful" that he will be able to walk again.


**Read**

**And**

**Advertise**

**In**

**ELETI-OFE**





## Nigerians Fin... ...omn... British Women

LONDON--Mrs Adanma Okpara, wife of the Premier of the Eastern Region, and Mrs Janet Mokelu, member of the Eastern Nigeria House of Assembly, have been meeting some of the leading "ladies behind the scenes" in British politics and finding that their problems similar are.

'It was such an enjoyable afternoon,' Miss Susan Walker, Deputy Chief Organisation Officer for the Conservative Party told a correspondent, after the eminent Nigerian ladies had visited her. 'We found we had so much in common,' Miss Walker added.

Mrs. Okpara had been particularly interested in the work of women in the Conservative Party and Miss Walker explained just how they organised themselves and the particular part they had to play.

CONFERENCE PRESIDENT

'Both she and Mrs Mokelu were delighted when I told them that a woman will preside over this most important Conservative conference in pre-election year,' Miss Walker added. This year's chaiman of the National Union of the Conservative and Unionist association to whom it falls to preside over the Annual Conference is Mrs. Peggy Shepherd.

'I have, of course met several Nigerian male Parliamentarians during Commonwealth Parliamentary Association conferences and courses, but this was the first time I had met Nigerian women politicians-and it was a thoroughly enjoyable and valuable experience,' she said.

## London Talk On Gambian Self- Government

LONDON—The Premier of the Gambia, Mr. David Jawara, who arrived in London recently, will be having talks with officials of the Colonial Office today.

The Commonwealth and Colonial Secretary, Mr. Duncan Sandys, announced some mouths ago that on recieving firm proposal from the Gambia, he is agreeable to the introduction of interral self-government in the territory.

It is expected that Mr. Jawara will be dicussing with oficials details of the proposals which the Gambia is to make.

Mr. Jawara is in London until Saturday 17th August when he flies to Israel for a private visit.

## Nigerians Win U.A.C. Scholarships

LONDON— There Nigerians and three Ghanaians are among eight new winners of Commonwealth schoolarships awarded by the United Africa Company, it is annonced in London.

The scholarships, for higher education at universities in Africa, have been awarded for one year in the first instance, and thereafter over the full period of study they will be renewed annually, subject to satisfactory reports

In addition, seven existng scholarships have been renewed for 1963/64.

The eight winners- two from Tanganyika-were selected from a short-list of fourteen who in turn were picked from a large number of applications by local committees in Accra, Lagus, Freetown, Bathurs, and Nairobi,

...ni ilẹ Yoruba odo- ...ti awọn Ẹgba ki fi ṣere, ni aiye ...a ma mbọ o, ti nwọn ma npa ẹran malu ... gbọ itan wipe ti nwọn ba ti bọ IYEMAJA yi tan awọn ara ilu a ma ni ifọkanbalẹ, gbogbo nkan a is ma toro.

## Lowo Awon Egba

Ṣugbọn odo na binu pupọ lọdun yi, o si ti di ya gbo yaju, gbogbo ile ati nkan ọgbin ni o ba jẹ, eyi mu ki awọn agbalagba ilu Ẹgba tori kori ki nwọn pa malu nla fun un. Boya eleyi le jẹki ẹja tuntun wọ inu omi ki ilu Ẹgba tun toro bi ti aiye atijọ.

## Alake Tuntun

Inu mi dun pupọ lati gbọ wipe ọrẹ mi, Ọmọ Ọba Samuel Adeṣina Gbadebọ, ti awọn Ẹgba fẹ ti jọba Alake tuntun dipo Ọba Ademọla ti o waja, ti wọ Ipebi ninu ọsẹ yi. Emi Ayinuka paapa ko ba ti lọ ki ỌBA KABIYESI ṣugbọn ẹkun omi ti o wa loju, ọna nissiyi ni ko jẹ ṣugbọn laipẹ yi Oba wa yi a ri ọwọ mi ki o to kuro ni Ipebi na. Kabiyesi!

... OLUBADAN ... a sọ ... mọ njẹ oye si bi o ti wu ki ne oloye na jẹ anfaani to sugbọn nisisiyi oju ṣe nla.

Mo gbọ wipe awọn Ijọba ibilẹ ilu Ibadan fẹ ko ile oye fun Olubadan kolubadan ti o ba njẹ. Ilẹ kan ti nwọn ti gba lọwọ awọn ọmọ onilẹ ni nwọn fẹ kọọ si, ọkẹ marun pọnun (£100,000) ni owo ti nwọn fẹ kọ afin tuntun na. Ara Ibadan, Okebadan yio gbe yin o!

## O-SA-DE-BE

Ki nto pari ọrọ mi ti ọsẹ yi, o yẹ ki nki ọrẹ mi atijọ Oloye Dennis Osadebay ti a ṣẹṣẹ fi jẹ Olotu Ipinlẹ Ijọba agbedemeji Iwọ Orun ku orire. Mo niran ọjọ ti a jọ nṣe ẹgbẹ ọdọmọde (Boy Scout) pọ l'Eko ati gbogbo igba ti mo wa mba a gẹgẹbi akọwe ibode (Custom Officer) ni Ẹhingbẹti l'Eko kanna. Ẹku atijọ mọ ara wọn ri. Ṣe o nran wipe mo ti fi igba kan sọ asọtẹlẹ wipe O-SA-DE-BẸ gẹgẹbi orukọ rẹ, Osodebay. Oye na a mọri o; ki o ba mi ki Obi Asaba ati Ọba Akewzua ni ilu Benin. Ẹ ku ofojuba iyawo rẹ Veronica ti o ṣẹṣẹ ti ilu Oyinbo de.



## BAYI NI A Nse E!

Aworan yi ni eyiti awọn Minisita alamojuto ikede ijọba awọn ilu ti o mba Ijọba ilu Gẹsi ṣe gba lọjọ ti nwọn lọ si ibi iṣẹ ti nwọn ti ngba aworan fun ẹrọ isọrọ si okere ti nwọn npe ni television ni ilu London. Gbogbo awọn Minisita alamojuto ikede ijọba ti o wa si ibi ajọ ipade nla kan ni ilu Oyinbo na ni nwọn gba aworan wọn fun ẹrọ isọrọ si okere ilu London.

## Dafidi Jale N Sosi Aguda O W'ewon

EBUTE-MẸTTA— A ki ja Ọlọrun lole ni a ngbọ ṣugbọn ọdaran kan ti nwọn npe ni Eko Davies jale ni Ṣọṣi, adajọ Kotu awọn ọlọpa ni Yaba sọ ọ sẹwọn ọdun kan gbako.

Ẹsun ti awọn ọlọpa fi ọdaran na sun ni wipe lọjọ kan o lọ gbadura owurọ ninu Ṣọṣi Aguda ti nwọn npe ni St. Paul's Ebute Mẹtta, bi o ti wọ ṣọṣi na tan kaka ki o kunlẹ ki o gbadura, idi apoti owo ti awọn ẹgbẹ alanu St. Vincent nda ni o gba lọ ti o gbe apoti na towo towo ti o wa ninu rẹ.

Ọga awọn ọlọpa ni bi ọdaran na ti bọ sna ti o nlọ ni awọn ti o nsọ Ṣọṣi na ba ki i mọlẹ; nigbati nwọn de teṣan ọlọpa ti nwọn ṣi apoti na ṣile mẹrin ati kọbọ mẹrin ni nwọn ba nibẹ.

Ọdaran bẹ adajọ wipe odarinjin on, o ni adura ni on lọ gba ki nwọn to durun mọ on.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street, Lagos
Phone 23370; Editor: (Olotu) Ọla Ọnatade, 15, Kosọkọ Street, Lagos, Box 467